# AWỌN ASỌTẸLẸ BALAAMU ATI IMỌRAN BUBURU RẸ̀

## Numeri 23:1-30; 24:1-25; 31:8, 16; 2 Peteru 2:12-17

### ẸKỌ 111 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Emi o bukun fun awọn ti nsúre fun ọ, ẹniti o nfi ọ ré li emi o si fi ré; ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye" (Gẹnẹsisi 12:3).**

**I A Ṣe Irubọ, A si Fun ni ni Awọn Asọtẹlẹ**

1. Balaamu paṣẹ fun Balaki lati mọ pẹpẹ meje ati lati pese akọ-maluu ati agbo fun irubọ, Numeri 23:1, 2
2. Balaamu lọ ṣe iwadi lọwọ Oluwa, o si pada pẹlu idahun, "Emi o ti ṣe fibú, ẹniti Ọlọrun kò fibú" Numeri 23:3-8; Isaiah 47:12, 13
3. Balaamu sọ asọtẹlẹ pe Israẹli yoo dá gbé, a ki yoo si kà wọn kún awọn orilẹ-ede, Numeri 23:9, 10; Deuteronomi 33:28; Ẹksodu 33:16; Efesu 2:14
4. Balaki n ṣe aroye pe n ṣe ni Balaamu n sure fun Israẹli nigba ti o ṣe pe fifi bu ni o n fẹ ki o fi wọn bú, Numeri 23:11
5. Wọn lọ sori oke Pisga, wọn mọ pẹpẹ, wọn ṣe irubọ, Balaamu si tun lọ wadii lọdọ Oluwa, Numeri 23:12-18
6. Idahun Balaamu, "Ọlọrun ki iṣe enia ti yio fi ṣeké", Emi gbà aṣẹ ati sure:. . . . . . emi kò si le yì i," Numeri 23:19, 20
7. Oluwa ko ri ẹṣẹ ninu Jakọbu, iho ayọ ọba si n bẹ ninu wọn, a o si wi nipa ti wọn, "Ohun ti Ọlọrun ṣe!" Numeri 23:21-24; Romu 4:7, 8

**II Awọn Asọtẹlẹ Si i nipa Israẹli**

8. Nigba ti Balaamu ri i pe o wu Ọlọrun lati bukun Israẹli, o doju rẹ̀ kọ aginju, o si ri Israẹli, Ẹmi Ọlọrun si wá sara rẹ̀, Numeri 24:1-4
9. O kigbe pe, "Jakọbu, agọ́ rẹ wọnyi ti dara tó, ati ibugbé rẹ, iwọ Israẹli!" Numeri 24:5
10. Bi afonifoji ni wọn tẹ́ lọ bẹẹrẹ, bi ọgba lẹba odò nla, bi igi aloe ti Oluwa gbin, Numeri 24:6; Orin Dafidi 104:16
11. Ọba rẹ̀ yoo si ga ju Agagi lọ, oun o si jẹ awọn orilẹ-ede ti i ṣe ọta rẹ̀ run. Eyi mu ki ibinu Balaki ru, o si sọ fun Balaamu ki o sa lọ si ibujoko rẹ̀, Numeri 24:7-11
12. Balaamu si tun bẹrẹ owe rẹ̀, "Emi ri i, ṣugbọn ki iṣe nisisiyi: emi si wò o, ṣugbọn kò sunmọtosi: irawọ kan yio ti inu Jakọbu jade wá, ọpa-alade kan yio si ti inu Israẹli dide." Bẹẹ ni "lati inu Jakọbu li ẹniti yio ní ijọba yio ti jade wá," Numeri 24:12-19; Ifihan 1:7; 22:16; Matteu 2:2; Gẹnẹsisi 49:10
13. O sọ nigba iparun awọn orilẹ-ede, o si wi pe, "A, tani yio wà, nigbati Ọlọrun yio ṣe eyi!" Numeri 24:20-25

**III Imọran Buburu**

14. Nipasẹ imọran buburu Balaamu, awọn Midiani mu ọpọlọpọ eniyan ni Israẹli dẹṣẹ, Numeri 31:16; Ifihan 2:14
15. Israẹli bá Midiani jà. A pa awọn ọba marun-un, a si pa Balaamu bakan naa pẹlu, Numeri 31:8
16. Peteru sọ nipa awọn ọmọ egun, ti wọn maa n sọ̀rọ "ẹgan si awọn oloye," "awọn oloju ti o kún fun panṣaga." A o pa wọn run patapata ninu ibajẹ ara wọn, wọn o si jẹ èrè aiṣododo, 2 Peteru 2:10-14
17. Wọn kọ ọna ti o tọ silẹ, wọn si tẹle ọna Balaamu, 2 Peteru 2:15, 16

## ALAYE

### Ipinnu

Balaki pinnu pe ki Balaamu fi Israẹli bú. A mọ pe awọn ọta Ọlọrun ki i jọwọ silẹ nipa ijatilẹ kan. Ọta alailaanu ni eṣu i ṣe. Nigba ti o dán Jesu wò ninu aginju, ko ni agbara lati mu ki Jesu jọgọ silẹ fun ebi ti o n pa A nipa pipaṣẹ fun okuta lati di akara, sibẹ eṣu ko jawọ kuro ninu igbiyanju rẹ̀. O tun gbe Jesu lọ si ṣonṣo oke Tẹmpili. O tun bá ijatilẹ pade. Lẹyin eyi, o gbe Jesu lọ si ori oke giga, o si lo ọgbọn arekereke ti o ga ju lọ, o fi gbogbo ilẹ ọba aye han An, o si ṣe ileri pe gbogbo nnkan wọnyii ni oun yoo fi fun Jesu bi O ba le wolẹ ki O foribalẹ fun oun. Wo Olurapada iyanu ti a ni! Ko si agbara ọrun-apaadi ti o le mu Un yà kuro ni ọna Ọlọrun. Okiki aye, ọrọ̀, ipo ati ọla ni O pa tì sí apa kan. Ohun kan ṣoṣo ti o leke ọkàn Jesu ni lati ṣe ifẹ ti Baba.

Balaki mu Balaamu lati oke giga kan de ekeji lati ṣe irubọ nibi kọọkan. Lai mọ Ọlọrun bi Balaamu ti mọ Ọlọrun, o ro pe a lè tipa bẹẹ mu Oluwa yi ọkan Rẹ̀ pada ki o si fi awọn eniyan ti O ti pinnu lati bukun fun titi ti akoko yii bú. Nikẹyin, nigba ti gbogbo akitiyan Balaki fidi-jalẹ, o sọ fun Balaamu ki o sá lọ si ibujoko rẹ̀ ati pe oun Balaki) ti rò

lati sọ ọ di ẹni nla, "Ṣugbọn kiyesi i, OLUWA fà ọ sẹhin kuro ninu ọlá." Ọmọ Ọlọrun tootọ yoo kuku yàn lati ni aṣẹ Oluwa lori igbesi-ayé rẹ̀ ju ọlakọla ti ayé le fun ni. Ohun iyowu ki o wà ninu ọkan Balaamu ni akoko yii, o mọ pe oun ko le tàbùku si ẹni ti Oluwa ko tabuku sí tabi fi ẹni ti Oluwa ko fi bú bú.

**Awọn Asọtẹlẹ ti O Tayọ**

Ninu awọn ọ̀rọ̀ ti Oluwa fi si Balaamu lẹnu lati sọ ni a ri diẹ ninu awọn asọtẹlẹ ti o jinlẹ ju lọ ninu Ọ́rọ Ọlọrun. Ni tootọ a ṣi i loju o si ri ọjọ iwaju.

Awọn ọ̀rọ̀ yii jẹ asọtẹlẹ ti o daju nipa ti iṣẹgun ti awọn eniyan Israẹli yoo ní lori awọn ọta wọn ati ni ti pe wọn yoo ni ilẹ Ileri naa. Bakan naa ni wọn tun n tọka si awọn iṣẹgun ti a o ri gba nipasẹ Jesu Kristi Oluwa – kiniun ẹya Juda – bori ẹ̀ṣẹ̀, ikú, ati Satani. Ayé ti ri imuṣẹ ọpọ ninu awọn asọtẹlẹ wọnyii, a si gbagbọ pe a n sunmọ akoko naa nigba ti a o mu gbogbo wọn ṣẹ. Alagbara ni Ọlọrun, agbara Rẹ̀ si bori ohun gbogbo. Oun le jẹ ki odi kẹtẹkẹtẹ sọ èdè ti awọn eniyan n sọ lati bá ọlọtẹ ariran wí; Ọlọrun si le lo, O si lo ètè ti ko fẹ lati sọ iyin Olodumare ati ti awọn ayanfẹ Rẹ̀, gẹgẹ bi o ti ṣe ni akoko yii. "Nitõtọ ibinu enia yio yìn ọ" (Orin Dafidi 76:10).

"Kiyesi i, awọn enia yi yio dágbé, a ki yio si kà wọn kún awọn orilẹ-ède." Lẹyin ẹgbaaji o din ẹẹdẹgbẹta ọdun, wọn ṣi jẹ eniyan ọtọ sibẹ. Kò si eniyan kan ti o lè sọ asọtẹlẹ yii. Kò si orilẹ-ède tabi eniyan ti a pamọ́ bi iru eyi. Ọlọrun nikan ni o le rí ọjọ-iwaju, ti o le mọ̀, ti o si le ṣe é.

**Ọwọ́ Agbára Kan**

Nisisiyi li a o ma wi niti Jakọbu ati niti Israẹli, Ohun ti Ọlọrun ṣe!" Awọn orilẹ-ède ti o wa ni ayika ti wa mọ otitọ yii pe Ọlọrun wà pẹlu Israẹli. Nigba ti awọn amí lọ si Jẹriko, Rahabu wi pe, "Emi mọ̀ pe OLUWA ti fun nyin ni ilẹ yi. . . . . . ati pe ọkàn gbogbo awọn ara ilẹ yi di omi nitori nyin. Nitoripe awa ti gbọ́ bi OLUWA ti mu omi Okun Pupa gbẹ niwaju nyin, nigbati ẹnyin jade ni Egipti; ati ohun ti ẹnyin ṣe si awọn ọba meji ti awọn Amori, ti mbẹ ni iha keji Jordani, Sihoni, ati Ogu, ti ẹnyin parun tútu. Lọgan bi awa ti gbọ́ nkan wọnyi, àiya wa já, bẽni kò si sí agbara kan ninu ọkunrin kan mọ́ nitori nyin; nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin, on li Ọlọrun loke ọrun, ati nisalẹ aiye."

Awọn eniyan ati awọn orilẹ-ede ti wọn yi awọn Ọmọ Israẹli ka mọ́ pe ki i ṣe iṣẹ Mose aṣiwaju, tabi agbara ati ipá awọn eniyan ti o n kó lọ ni o n mu awọn eniyan naa tẹ siwaju si iru iṣẹgun bẹẹ; ṣugbọn pe Ọlọrun kan wà ni Ọrun ẹni ti ọwọ agbara nla Rẹ̀ nà jade fun eniyan kan ti O pinnu lati bukun fún. Awọn eniyan miiran le maa gan Ọlọrun ki wọn maa ṣépè, ki wọn si maa sọrọ-odi si orukọ Rẹ̀, ṣugbọn jẹ ki Oluwa gbé ọwọ agbara Rẹ̀ soke, wọn a si daamu, ọkàn wọn a si di omi fun ibẹru.

**Awọn Asọtẹlẹ Nipa Jesu**

"Lati inu Jakọbu li ẹniti yio ní ijọba yio ti jade wá." Asọtẹlẹ agbayanu nipa Jesu! Nigba ti a ba ro bi o ti pẹ to sẹyin ti a ti fun ni ni asọtẹlẹ yii o ya ni lẹnu irú ifihan ti Ọlọrun fun Balaamu.

Gbogbo awọn ẹda oju ọrun ni a kà si ohun ami ọba. Nigba ti o sọ nipa Irawọ kan ti yoo ti inu Jakọbu jade wa ati Ọpa Alade kan ti yoo ti inu Israẹli dide, o n sọ asọtẹlẹ pe Ọba kan n bọ̀ ti yoo ni agbara lori gbogbo ayé. Ọdun pupọ lẹyin eyi, a ti ipa irawọ kan tọ́ awọn amoye wá si ibi kan nibi ti a gbé bí Ọba naa si.

Angẹli naa kede fun Maria pe, "On o pọ̀, Ọmọ Ọgá-ogo julọ li a o si ma pè e: Oluwa Ọlọrun yio si fi itẹ Dafidi baba rẹ̀ fun u: yio si jọba ni ile Jakọbu titi aiye; ijọba rẹ̀ ki yio si ni ipẹkun" (Luku 1:32, 33). A sọ eyi fun Maria ni ọpọ ọdun lẹyin ti Balaamu ri iran rẹ̀. Ọrọ asọtẹlẹ Balaamu ti o bẹrẹ pẹlu: "Emi ri i, ṣugbọn ki iṣe nisisiyi: emi si wò o, ṣugbọn kò sunmọtosi," fi hàn pe ohun ti oun ati angẹli ti o wa sọ nipa ibi Jesu n sọ jẹ nipa ohun kan ti o n bọ wa ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju. Akoko kan n bọ ti gbogbo eniyan ti o ti gbe ni ayé rí yoo duro niwaju Ọpa Alade naa ti wọn yoo si gbọ́ idajọ nipa ipin wọn ni ayérayé. "Gbogbo wa ni yio sá duro niwaju itẹ́ idajọ Kristi" (Romu 14:10); "Mo si ri awọn okú, ati ewe ati àgba, nwọn duro niwaju itẹ;….a si ṣe idajọ fun awọn okú . . . . gẹgẹ bi iṣẹ wọn" (Ifihan 20:12).

**Imọran Buburu**

Lẹyin ti Oluwa ti fi ibukun ti yoo jẹ́ ti Israẹli ni ọjọ ikẹyin han Balaamu, wolii naa yí si apá kan, o si fi ọna ti awọn Midiani lè gbà tan Israẹli sinu ẹ̀ṣẹ hàn. Ko ya ni lẹnu pe Peteru ati Juda sọrọ ti o le nipa nnkan yii, wọn si fi Balaamu ati awọn eniyan bi ti rẹ̀ wé ikuuku lai si omi, ti a n ti ọwọ afẹfẹ gbá kiri: omi okun ti n ru, ti n ho ifofo itiju ara wọn jade; alarinkiri irawọ, awọn ti a pa okunkun biribiri mọ de laelae (2 Peteru 2:15-17; Juda 12, 13).

Juda tun sọ pe "awọn angẹli ti kò tọju ipò ọla wọn, ṣugbọn ti nwọn fi ipò wọn silẹ, awọn ni o pamọ́ ninu ẹ̀wọn ainipẹkun nisalẹ òkunkun de idajọ ọjọ nla ni." A pa Balaamu ninu ogun pẹlu awọn ọta Oluwa.

**Ikilọ**

A kilọ fun wa pe ni ikẹyin ọjọ igba ewu yoo dé nigba ti awọn eniyan yoo jẹ olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun.

Nigba ti Balaamu wo ọjọ iwaju ti o si ri bi Oluwa yoo ti bukun fun Israẹli ni ikẹyin ọjọ, o fẹ ki igbẹyin oun dabi ti wọn. Ṣugbọn a ri i pe ko fẹ san ohun ti yoo gbà á lati ri ibukun naa gbà. Ọpọ eniyan ni wọn dabi Balaamu: wọn a maa fẹ lati ni ibukun Oluwa ni igbẹyin ọjọ ayé wọn, wọn a si maa fẹ ki a mu wọn lọ si Ọrun nigba ti wọn ba kuro ni ayé yii. Ṣugbọn wọn n fẹ aye nigba ti wọn wà láàyè. Wọn ko fẹ mu oju kuro ninu faaji ayé ati ọlá rẹ̀ ki wọn ba le ni iye ainipẹkun nikẹyin.

Mose jẹ apẹẹrẹ rere ẹni ti o n fẹ kọ ohun gbogbo silẹ ki o ba le tẹle Jesu. Mose fi itẹ-ọba silẹ, ọlá, ọrọ̀ ati okiki, o kuku yàn lati maa bá awọn eniyan Ọlọrun jiya ju ati jẹ faaji ẹ̀ṣẹ fun igba diẹ (Heberu 11:25).

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni Balaki mu Balaamu lọ lati lọ rubọ?
2. Lori pẹpẹ meloo ni Balaki ru ẹbọ?
3. Ki ni ẹ̀ṣẹ Balaamu?
4. Orilẹ-ede wo ni o fi ẹtan mu Israẹli dẹ̀ṣẹ nipa imọran buburu Balaamu?
5. Apẹẹrẹ ta ni Irawọ naa ti o n ti inu Jakọbu jade wa i ṣe?
6. Ki ni itumọ pé Ọpa Alade kan ti inu Israẹli jade?
7. Darukọ diẹ ninu awọn asọtẹlẹ ti Balaamu sọ ti a ti mu ṣẹ.
8. Darukọ diẹ ninu awọn asọtẹlẹ ti a gbagbọ pe a o mu ṣẹ lai pẹ.